Akiyesi

Anfọ Eniti yio ma ba wa ta Iwe Irohin Imọlẹ. Ni agbegbe Ilọrin tabi Ilumiran. E kọwe si ọdọ Ọgbẹni: R. O. Adedeji Esq Ni P. O. Box 12 Ilọrin



# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ-DE, OKUNKUN PARADA.



AKIYESI

E ma polowo ọja yin sinu Irohin Imole



VOL. III No. 138 MONDAY FEBRUARY 22 – FEBRUARY 28 1960 KỌBỌ KAN (1d)


# Enmo nla tun de o, pagidari Omo odun merindinlogun

AWA IWE IROHIN IMỌLẸ RI IROHIN GBỌ LATI ILU OKERE NI MEGALAMBU NI MALAYA PEỌMỌ ỌKUNRIN KAN TỌJỌ ORI RẸ JẸ ỌDUN MẸRIN-DINLOGUN GBE OBINRIN ARUGBO KAN TI ỌJỌ ORI RẸ JẸ ỌDUN MERINDIN-LOGỌTA NI IYAWO. ELEYI JẸ OHUN TI O YA GBOGBO ENIA LẸNU O SI TI FA IBINU ỌPỌLỌPỌ AWỌN ARA ILU LỌMỌDE LAGBA NINU, WỌN NI NIṢE NI OBINRIN ARUGBO NA FI EGBOGI FA ỌDỌMỌ-KUNRIN NA, BI KO BA ṢE BẸ NI WỌN NI AWỌN KO RI OHUN TI O LE FA A PE KI IFẸ WA LA-RIN AWỌN ẸNI MEJEJI YI.

Awọn Mejeji polowo ara won sinu Iwe Irohin kan ti antẹ ni ede Chinese pe awọn ti ṣe igbeyawo, aworan ti awọn mejeji jijọ ya jade pẹlu ipolowo na. O jẹ aṣa ti ko ṣowọn larin awọn (Shamisi) Chinese ni Malaya lati ṣe igbeyawo iru eleyi. Awọn ara ilu nkun sinu kun sode ni-pa ti ọdọmọkunrin yi, a ni papa Iya rẹ ti o jẹ ẹni adọ-ta ọdun, ti iyawo ọmọ rẹ si fi ọdun mẹfa julọ ko fẹ ki ọmọ on ṣe idapọ igbeyawo yi, nitori o ni arugbo ni ọmọ on fẹ, nigbati awọn ọmọ oge ati jaiye-jaiye kunlẹ lai ri eni fẹ wọn.

Omọkunrin yi ni niwọn igbati ifẹ ba ti wa larin on pẹlu arugbo yi, bi o ti lọ jẹ ẹni ọgọrun ọdun kosi eyi ti e kan ẹnikankan. O ni loju ti on o, kosi Obinrin ti o ni ẹwa to Iya Arugbo yi. Pẹlu idunnu lo tun fi sọ wipe iya iya on yi ti ni oyun oṣu meji fun on.

Onirohin kan fi ye wa pe Obinrin Arugbo yi ti fi igba kan fẹ Pokun so ri, nigbati won gba Ọdọmọkunrin yi ni ọwọ rẹ, ọpẹlọpẹ awọn Ọlọpa, niṣe ni wọn gbe e lọ si Ile iwosan kan ti wọn si mu Ọdọmọ-kunrin yi wa ba a, iyẹn dẹ tun ṣe adehun fun pe Ekuro la la baku Ẹwa.

Ni oṣu kẹwa ọdun tokọja ni wọn pade ara wọn ni ile oriṣa Chee Kew, Kok Tet orukọ tọmọkunrin yi njẹ, lọ si ile oriṣa lati lọ ṣe ajọdun ọdun awọn oriṣa mẹsan ti wọn nṣe lọdọdun ni ilu wọn. Larin ajọdun yi ọpọlọpọ ni ẹgun ma ngun tobẹ ti wọn ma nfi ọbẹ, ida, ọkọ gun ara wọn tabi ya ara wọn, ṣugbọn ko ki ndun wọn; ibi gan ni ifẹ ti bẹrẹ fun ọmọge ati arugbo yi.

Ọsẹ diẹ lẹhin ajọdun yi, niṣe ni Kok Tet dẹ bẹrẹ si


WO OJU EWE KERIN


## gbe egbe iya iya re ni iyawo


## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ẹrọ Alata todaraju gbogbo eyi ti wọn ti nlo tẹlẹrilọ lẹyin ata lilọ o tun le lọ Igbado ati Ọka Baba ati Ẹwa - ere orisirisi.

£45 Ni a nta Pẹlu Enjinni Pẹtrol tabi ati pẹlu Elẹtiriki Mutọ.

O WA NI ṢỌBU:-

**Akoshile Brothers,**

5, Balogun Street West,
P. O. Box 599.
Phone No., 24395. LAGOS.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pa taki ta ṣe ni Aṣẹpe fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idanilojo fun Awọn iṣẹ ribiribi ti o ti nṣe. MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara pupọ fun igbona ikọ, otutu, Aiperi, Osi inu ọmọde, jẹdi jẹdi Kokoro ori ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hihu jẹ irọrun fun awọn ọmọde, osi njẹki awọn ọmọde tobi. osi nmu wọn dan ni awọ Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko-ṣe mani fun awọn ọmọde. Ijalara lewu pupọ, tete lọ ra ti ẹ ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere rẹ jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d
LILO RẸ- Jibi kekere kan lemẹta lojumọ

*Wholesale Distributors*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West, Lagos Nigeria. Phone 22515
34, Docemo Street, Lagos. Phone 204247

# IMOLE

EUN ỌRỌ WA:-
IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA

*Editorial Works & Office*
16, Bamgbose Street, Lagos.
Telephone - 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street.


## Faranse ilu awon Olori kikun

Haa! Faranse o ṣe eleyi tan, mọ wipe Ọlọrun a t i itan yin da yin lejọ. Lẹhin ẹ b ẹ, ijiroro, lẹhin igbati gbogbo agbaiye ti fi ẹ n u ṣe ọkan pe ẹtu oloro ti o lẹ danwo ni ilẹ Afrika ti o nfi ojukokoro ati eru pe ni tirẹ ko dara fun alafia ara aiye, o ko jale o si ṣe ori kikun, o wa dan ẹtu oloro na wo. "Lotito lotitọ ni a wi fun yin, Ẹlẹṣẹ ko ni lọ lai jiya. (Ọrọ Jesu ninu Bibeli) O si da wa l o j u gedegbe pe Faranse ko ni lọ lai jiya ẹṣẹ iparun rẹ.

O wa yẹ ki gbogbo wa wo ohun kan wo, ohun na binu ni, ṣugbọn ṣibẹ ohun ribiribi ni, ohun na ni pe ti ilu kan ba fi aṣiwere ṣe olori rẹ, gbogbo ilu na ni were, bẹ gan-gan ni awọn Faranse. Ọrọ Ọlọrun ko le ṣe ki o ma ṣe, ọrọ Ọlọrun ninu Psalm sọ wipe "Aṣiwere sọ ninu ọkan rẹ pe Ọlọrun ko si" bẹ gẹgẹ ni awọn olori Faranse wi ni ọjọ kini lẹhin roghodiyan kan ri, nitori ni wọn la ẹnu ori wọn gadagba lati sọ pe "Awọn ti gbe Ọlọrun kuro lori itẹ, awọn de ti g b e ogbọn dipo rẹ" A lero pe ẹ wa ri wipe aṣiwere aiye, aṣiwere orun patapata gba ni Faranse, nitorina ni ko ṣe jẹ iyalẹnu f u n wa pe lẹhin ẹbẹ kakiri aiye, nitori ni wọn ko jale ti wọn ṣe ori kikun ti wọn si yin ẹtu oloro na.

Iwe "IROHIN IMỌLẸ" wa fẹ da ni imoran pe ni iwọn igbati Faranse ti tun sọ wipe awọn ṣẹṣẹ b ẹ r ẹ idanwo ẹtu oloro ni Sahara ni, atipe awọn yio tun dan imiran wo ni oju meji sii, o wa yẹ ki awa ọmọ ilẹ Afrika mọ ibiti a nlọ, o yẹ ki gbogbo enia ilẹ Afrika ṣe ipade, ki a mọ ọna ti a o gba lati doju i j a ko Faranse, awọn ... ti ija pẹlu ... ki a ... bi akin enia, inibi ati g... gbe pe akin ni awọn t... ẹ ṣe orile ede wa ni, ẹkan ni ọmọ ọkanrin nku, ti a ba kuku ku lẹkan, o san ju pe ki a ma joro, ki a si ma ku diẹdiẹ lọ. AFRIKA D I D E. FARANSE TI KAN Ọ LARAN.

O yẹ ki gbogbo agbaiye mọ pe ohun kohun ti o ba ṣẹlẹ, ki ṣe ọjọ wa ni Afrika, o kuku san ki gbogbo rẹ daru ju ki omugọ pa wa run lori ilẹ aiye. Eleyi to ẹnyin alawọ funfun, o wa yẹ ki ẹ mọ ọna ti ẹ o le fi di ọrẹ wa, ole, Igara ati alọnilọwọgba yin ni ilẹ Afrika ti to.

## Ọjọ onileto gbe ileto ti koja ni Naijiria

OLOYE S. L. AKINTỌLA. Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria sọ ni Ibi ase kan ti awọn Ọmọ ẹgbẹ ti Ogbomọshọ Parapọ se fun ni Ibadan lẹnu lọlọ yi pe' Ọjọ Onileto gbe Ileto ati pe Onile gbe ile ti di itan ni Ilẹ Naijiria.

Oloye Akintọla nfesi si ọrọ ti a sọ nipa rẹ, o tun sọ wipe on ni Anfani lati kọ ẹkọ rere lati ọwọ awọn O l u k ọ n i Enia dudu ati Amerika ti o fun on ni ẹbun ati ma fi tọkantọkan ati tara-tara ṣiṣẹ.

Awọn Enia Ogbomọshọ Oloye Akintọla wipe won jẹ akinkanju enia nwọn si lemi fiẹ ilọsiwaju ilu wọn. Oni ou lero pe wọn yio tun tẹ ara mọ dida owo ti wọn nda fun ilọsiwaju ilu Ogbomọshọ ni pataki ati Naijiria.

Ọmọba Ladunni Laoye ni o kọkọ sọrọ nipa Oloye Akintọla, o ni Oloye Akintọla dabi irawọ giga atipe o jẹ omiran enia ni inu oye. O tun wa ṣe afikun wipe idoju ati ifitọkantọkan ṣe iṣẹ ni o gbe Oloye Akintọla de ipo ti o wa loni.

Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ papa tun sọrọ iyin ati igbega nipa Oloye Akintọla. O tun sọ wipe Ipinlẹ I w ọ Orun ni ori ire nipa pe wọn ni Olotu ti o ye koro ninu Oloye Akintọla, ni awọsun Ominira Naijiria, nitoripe lẹhin Ominira ao nipa awọn ilu okere yio po si i, a si niu ero Ilu pọ si i.

Oloye Awolọwọ wa yin awọn Osiṣẹ Ọlọrun nitori ipa ti sa si ilọsiwaju wr.

Larin awọn ti o wa nibi ase na ni Olubadan I. B. Akinyẹle, Ọ g b ẹ n i D.A. Murphy Igbakeji Gomina Iwọ Orun Ọmọba Adeleke Adedoyin ati aya rẹ, Oloye J. A. O ebiyi ati ọpọlọpọ enia ti aye kosi.

# IWE SI OLOTU

## Petepete T'ana Ni Popa (Eko

GBOGBO ENYIN ONKAWE Irohin Imọlẹ, mo kiyin jake-jado, Ọlọrun ko ma fi owo wọn gbogbo wa. o, kẹ sa ma ra Irohin I m ọ l ẹ lọsọsẹ, ẹ o si ma gbọ ọrọ mi dada. Mo ro wipe gbogbo yin lẹhun gbadun mi

Gẹgẹbi mo ti sọ fun yin tẹlẹ, pe Takute Pẹtẹpẹtẹ tana ni Popa ko ti ri nkan mu wa lọsẹ yi, nitorina ngo ma fi itan Aladun dayin lara ya dada. Itan t'ọsẹ yi niyi:—

"ANU KI NPANI - IBI NI NPA ENIA"

Baba Alanu mura, on lọ si oko rẹ, nigbati o se Baba Alanu pade Ejo kan lona, Ọdẹ kan nle ejo yi bọ; bi Ejo ti pade Baba Alanu, o bẹẹ pe" ki o jọwọ ki o sanu on. O ni Ọdẹ ni o bẹrẹsi lemi lati pami, bi mo ba fi ara mi pamọ sibiti ọdẹ na ko tile ri mi, yio sa wa ba mi ni ibẹ, nitorina mo bẹ ọ baba alanu ki o jọwọ g b e mi pamọ si inu rẹ, o ko ni pade agbako lailai. Baba alanu ni ko buru, ni otitọ baba alanu ni mi, nko si gbọdọ ma ṣe anu na fun ọ. Kia, baba alanu ti la enu rẹ, o si gbe e j o yi pamọ si inu rẹ titi ọdẹ na fi kọja lọ.

Bi ọdẹ na ti mbọ ti o pade b a b a alanu, o ni "Baba, njẹ o ba mi ri ejo nla ti o kọja lọna ti o mba bọ bayi? Baba alanu ni rara o, nko gburo ejo, bi mo ti mbọ lati ile niyi, mo nlo si oko mi ni Ọdẹ ni ha! ejo titobi yi ti lọ, omaṣe o, ko buru.

Nigbati Ọ d ẹ lọ tan ni Baba Alanu pe ejo inu rẹ "Ejo! ejo!, ọdẹ ti lọ o, wa jade kuro ni i n u mi ki o si ma ba ọ n a tirẹ lọ o, Ejo ni "Baba Alanu Ba ako - Daya họwu! họwu! iwọ ri Eru ti o lọ si I l u tẹ ti a s ọ p e o si ri ni?

WO OJU EWE KẸTA


Make a friend!

offer GALLEON

NIGERIA'S FRIENDLY CIGARETTE

tastes expensive
...costs so little
penny a stick!
1/8 for 20



## O BERE LATI OJU EWE KEJI

mo ti de Ile mi, nko si le jade mọ. Bi ọ ba si di pe mo ni lati jade, mo ni lati jẹ gbogbo ẹ d ọ oke, ẹdọ isalẹ tio wa ninu rẹ ki to jade.

Ye! ye!! ejo i w ọ fẹ fi rere san ibi fun mi ni? jọwọ jade jade kia-kia. Ma bami se ere esu e, kia ni Alanu wi. Ọgbẹni Ejo tun fesi, oni "Rara, rara, ko si ohun ti o le mu mi jade, ko tilẹ si Ọlọpa na to le fami jade p ẹ l u. Baba Alanu ni o "o dara b'oba jẹ otitọ ni on sọ iwọ ejo, jẹ ki a lọ ọdọ igi ọsan ti o wa lọkan-kan yẹn, ki a si ro ejọ fun uu. Bi o ba sọpe iwọ lo j a r e, ko se ohunkohun to ba fẹ fun mi Bi iwọ ejo lo ba jẹbi, ao ma gbo bi a b a de ọhun.

Nigbati wọn de ọdọ igi ọsan, Baba Alanu ro ẹjọ fun igi ọsan, ni igi ọsan das lohun. Wo mi, ko si anu l'aiye, ṣe ori bi Ọlọrun ti da mi? O d a m i pọlu eso rere, ṣugbọn awọn ọmọ Araiye wo mi titi nwọn fi ada ge igi pompo-po-mpo lati ma fi ja eso darati o wa lori mi, ko si ejọ ti mo le da Ejo, ile rẹ lo wa lotọ gegebi o ti sọ.

Ko pẹ diẹ ti wọn kuro lọdọ igi ọsan ni Baba alanu ri emi Pẹtẹpẹtẹ Tana Ni-Pọpa. Baba Alanu bẹre i kigbe "Duro de mi o, Pẹtẹpẹtẹ Tana ni Pọpa duro ki o gbọ ohun ti oju mi ri mo ti ku tan o. Mo bere pe kini de B a b a Alanu? Baba alanu ko ẹjọ o ro fun mi. Nigbati mo gbọ tan, mo kigbe; Ha! Baba alanu iwọ ko mọ iwa Ọgbẹni ejo tẹlẹ-tẹlẹ ni? koburu jẹki ngbọ ti Ọgbẹni ejo, na, ki nto mọ e j ọ ti ngo da. Ngbo, ki lo ti ri Ọgbẹni Ejo.?

Ejo papa ro ẹjọ tirẹ: ko si bi o t i r i ju bi o ti sọ fun yin lọ ko si ẹniti o le fagbara mu mi jade o, ko tilẹ si rara ni.

Emi Pẹtẹpẹtẹ Tana Ni-Pọpa sọpe'i ko buru o, ejo ododo lo sọ, ṣugbọn ko yẹ sa ki nma ba ọ sọrọ ki o ma tilẹ le yọri sita diẹ lati le wo mi loju nitoripe oju lọrọ wa. Ejo ni o yẹ hẹ; bi ejo siti yọ ori sita ni emi Pẹtẹpẹtẹ fa a j a d e ninu ikun Baba Alanu. Inu Baba Alanu yi dun pupọ.

O dupẹ pupọ lọwọ mi fun ore iru ọ g b ẹ n bayi.





ṢỌRA FUN

OTUTU IBA




Da OTUTU IBA rẹ duro

gbe koro "ASPRO" meji mi

ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA

# MA FI OWURO S'ERE APA 5

Lati Qwo' J. O. SHOVINKA Mushin)

BI WỌN TI JẸUN tai jẹun tan si Omiran Apara yọ si nwọn, ki nwọn lo yira pada o ti da ẹwọn si wọn lọwọ ṣakaṣiki, o si ko wọn sinu ago bi Adiẹ.

Gbogbo wọn wa nwo koran, ohun ti o dẹruba wọn ni pe ẹyọ ika kanṣoṣo ni Omiran yi fi kọ ago ti o ko wọn si, o si nlọ rẹ-rẹrẹ.

Nigbati o de ori oke tente kan o joko, o fi idi ago yi silẹ pẹ ẹ, awọn ti o wa ninu ago bẹrẹsi f'ori sọra wọn. Omiran Apara Gende Ọlọrun funrarẹ mi kanlẹ hẹẹn!, Oke papa mi tititi, apata san kẹkẹ-kẹ.

Awọn yoku ti dọodin a fi Mafarọṣere fi o ke ni gbolohun kan pe ha! awa ṣegbe o. Nigbati Omiran Apaara gbọ bayi, o bu sẹrin kaaka-kaa, iro ẹrin rẹ papa dabi igbati Aara nsan ategun ti o njade lẹnu rẹ dabi iji lile, ohun ti o jẹ iyanu julọ ninu iwa Omiran Apaara ni pe ti o ba nrẹrin, omi ma nbọ loju rẹ poroporo ni.

Ko ju iṣẹju meji lọ ti o bẹrẹsi rẹrin ni Oke nla yi lanu ho o, o i jin lọ gburu-gburu, bi Mafarọṣee ti ke to pe ha! ha! iru Enmọ wo leyi? Ọlọrun o. Bẹ ni Ojola kan ti o gun ni ẹsẹ aimoye nyọrun bọ tan-an lati inu iho yi, iṣẹju aya o ti we mọ ago ti awọn Mafarọṣere wa ninu rẹ, ogbirigbira ni o yi nwọn wọ iho nla na. Ọ bun na si anu de mọ nwọn.

WỌN KO RI OJOLA MỌ

Nigbati wọn de iṣalẹ ogbun jingbun jingbun tan; nwọn ko ri Ojola mọ.

Omiran Apaara ni o yọ si wọn garan, o si wipe alafia fun nyin, ibẹru ko si jẹki nwọn dahun a fi Mafarọṣere ti o dahun pe " Alafia ko ọ. Omiran Apaara tu nwọn silẹ ninu ago o si lọ fa wọn le Onibode lọwọ.

Egbẹgbẹrun ọna ẹgbẹrun enia ni o wa ni abẹ itọju Onibode yi, nigbati awọn Mafi owurọṣere papa foju kan awọn igbekun yi ọkan wọn wa balẹ pẹṣẹ.

Mafarọ Ṣere ni ṣe awọn ẹda ọwọ Ọlọrun na niwọnyi.? Gbogbo ohun ti o ba de, amuwa Ọlọrun ni, a ti faramọ o Onibode fun wọn ni onjẹ, ṣugbọn ẹnu wọn ko ran nitori ipaya

OMIRAN BẸRẸSI BA NWỌN SỌRỌ.

O NI Ẹnyin dejadeja ile Aiye, agbonrin ṣe jamba Ọmọ Adamọ, ẹ ba Ile aiye jẹ tan, ẹ fọ tutu pẹlu iwa buburu, ẹ ko fi mọ nibẹ, ẹ tun gberaso lati wa dan Ọlọrun Ọba wo, ẹ fi ile aiye silẹ, ẹ gba Ọrun wa lai ti ku. Ha! ọmọ araiye ẹ ma ni ipa o.

Ẹgun gangangan ni ẹ tapa si yi. Ẹniti o ba ṣe nkan ti ẹnikan ko ṣe ri, yio si ri ohun ti ẹnikan ko riri. Ohun ti ẹ fọwọ nyin fa yi, ẹ ko ni gbagbe lailai.

Akiyesi:— Lọse to mbọ lagbara Odua ẹ o ma ka ohun ti oju nwọn ri. Olotu aiye ayẹ ọ o.

## Irawo nyin fun Ose yi

Aquarious (Jan 20-Feb 18) Eni keji rẹ yio wa ọ wa lati ba lọ sode lọsẹ yi

Piesces (Feb 19-Mar 20) Ifa ati ẹbun ni fun ọ ni ọsẹ yi.

Aries (Mar 21- Apr 19) Iyanu nla fun ẹniti o ni ifẹ si

Taurus (Apr 20-May 20) Wa ohun ti o le mu inu rẹ dun.

Gemini (May 21- June 20 Ona lati fi ohun kan di ekeji yio bọsi.

Cancer (Jane 21-July 20) Aye wa lati ba ẹniti o fẹran ninu ẹbi rẹ di ọrẹ imulẹ.

Leo (July 23-Aug 22) Ona kan ti o tigba lati tun igbesi aiye rẹ ṣe yio ṣẹṣẹ wa jade.

Virgo (Aug 23-Sept 23) Ṣe eto ki o le ri ori ire.

Libra (Sept 23-Oct 22) Eto ti yio yọri si rere ṣe e ṣe.

Scorpio (Oct 23-Nov 21) Ọsẹ to dara fun ohun gbogbo

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, Lagos Phone: 21985.
Olotu: E. A. Adeniji No. 51, Tejuosho Street Surulere, Yaba

FUN OWO "IROHIN IMOLE" ODUN KAN
EKO— Ṣile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin (4/4d)
Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Ṣile Mẹfa ati Kọbọ Mẹfa (6/6d.)

# Omoge gbe Arugbo Olodun Merindinlogota ni iyawo.

O BERE LATI OJU EWE KINI

lọ ba iya arugbo yi wa egbogi ninu iho okuta ni aginju arugbo yi wa soọ di eni pataki ninu awujọ oriṣa.

Niṣe lo kọ jalẹ yẹyẹ ti awọn ẹgbọn rẹ ati awọn ore nfi se, ti o wa fẹ obinrin arugbo yi. Iya Kok Tet binu patapata nigbati o gbọ Irohin Igbeyawo ọmọ rẹ.

Awọn Ara Ilu ro igbeyawo na si ohun ti iṣe Ifẹkufẹ. O yẹ ki ẹnyin Onkawe wa mọ pe ogbo nkangi Adahun se ni Obinrin Arugbo ti Odọmọkunrin Kok Tet yi fẹ o.

Nisinyi wọn ko ti ni eto ibi ti wọn yio gbe nitori wọn ti wo Ile nwọn ni Mengambu, wọn ti kọkọ salọ si Kuala-Lumpur, ṣugbọn sibẹsibọ abami ifẹ yi si nya gbogbo Enia lẹnu. Ibiti a gbọ nipare niyi, bi a ba ti tun gbọ nipa rẹ si, Ẹ o tun ma gbọ nigba-miran.


# KERE O. AKIYESI PATAKI

'Awa na le jeri wipe ojulowo haunhaun Egbogi digi ni LEOPILLS', Awa na si nlo ni ilu wa Gold Coast (Ankara) Ghana pelu, meji rẹ kosi ninu gbogbo oriṣiriṣi Egbogi kakiri ilu Naijiria.




## Irohin Kakiri Igboro Ilu Eko

Bẹna si ni ẹwẹ ni igboro ilu Eko, irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia, tomọde ti agba ni asiko yi ti wọn si nfi se ọrọ ati orin kọ larin ara wọn jẹ nipa ti egbogi Jamani olokiki yi ti wọn npe ni 'Leopills'.

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti wọn ṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe Bi o ti Lagbara to, ti o jẹ ojulowo giriki ati atamatase fun iwosan JẸDIJẸDI bio ti wun ki ọjọ rẹ ti le pẹ to, bẹna si ni awọn tun le fi ọwọ sọ aya tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi aisan bi Akọ Inarun, Lakuregbe, Ejẹ dudu lara, Arun Ẹdọki, Iju Igbẹsise, tabi Aikori Igbọnsẹ dede. Inu-rirun nigbakugba, Ara-wiwo, Esanri, Ẹhin-didun, Oju-ṣiṣu tabi aiko riran kedere, Kokoro buruku lara, Osi inu, Onigbameji, ati oriṣiriṣi arun miran gbogbo pelu, 'WIPE' wọn yio ri alafia ni kiakia bi wọn ba nlo egbogi 'LEOPILLS' nitoripe asi ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa sisọ di ọtun patapata.

SE IRANTI PE ALAFIA NI OGUN ỌRỌ
IJAFARA SI LEWU PELU O (POSTAGE 1/9d)
Egbogi Leopills:- Igo nla Ṣilẹ mefa pere ni.
Igo Kekere:- Ṣile mẹta abọ pere ni

Bere ojulowo Egbogi omiran fun oriṣiriṣi amodi ti o ba fe ni ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palm Church Street, P. O. Box 333
Lagos Nigeria Phone 22878
Ati Pelu Ni Sobu Arabinrin:-
MRS. C. O. BABAJIDE,
NEAR HEALTH OFFICE: IBADAN
ati ni ABIMBỌLA MEDICINE STORES
B29 Okesha Street, Ilesha

KIYESI:— Ri daju gbangba wipe sọbu ti wọn nta lo gbe ranṣẹ lọra, bi bẹkọ awọn elomiran yio fi ERU lọta adamọdi tabi orisi omiran fun ọ o, maṣe gba rara.